# ORIN NIPA ỌGBA-AJARA

### Isaiah 5:1-30

### ẸKỌ 349 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Egbe ni fun awọn ti npè ibi ni rere, ati rere ni ibi, ti nfi okùnkun ṣe imọlẹ, ati imọlẹ ṣe okùnkun” (Isaiah 5:20).**

### Iṣura Ọwọ́n fun Ọlọrun

Ọlọrun fẹran awọn ayanfẹ Rẹ̀, awọn Ọmọ Israẹli. Nigba kan O pe wọn ni “iṣura ãyo” Rẹ̀ (Orin Dafidi 135:4). O wi pe, “Mo fi okùn enia fà wọn, ati idè ifẹ” (Hosea 11:4). Nigba ti orilẹ-ède Israẹli bọ́ kuro ni oko-ẹrú Egipti, Ọlọrun wi pe, “Mo ti rù nyin li apa iyẹ́-idi, ti mo si mú nyin tọ̀ ara mi wá” (Ẹksodu 19:4). Wò bi Ọlọrun ti fẹran Israẹli tó!

Ṣugbọn Israẹli ti fi aimoore fàsẹyin kuro ninu ifẹ yii, wọn si n bọriṣa dipo ki wọn sin Ọlọrun. Wọn kò mọ rírì gbogbo ohun rere ti O ti ṣe fun wọn; wọn si kọ̀ lati gbọran si aṣẹ Rẹ̀.

### Orin Isaiah

Ni ọjọ kan Ọlọrun sọ fun Isaiah wi pe ki o kọ orin lati rán awọn Ọmọ Israẹli leti ohun ti Oun ti ṣe fun wọn. “Nisisiyi, emi o kọ orin si olufẹ ọwọ́n mi, orin olùfẹ mi ọwọ́n ni ti ọ̀gba àjara rẹ̀.” Jesu ni “ayanfẹ” Ọlọrun O si fi Israẹli wé ọgbà-ajara kan lori okè ẹlẹtù loju, ọgbà-ajara ti a sọ ọgba yika rẹ̀.

Ọlọrun ti fi Ilẹ Kenaani fun Israẹli, O si ti sọ ibi ti aalà ilẹ wọn dé fun wọn. Aalà wọnni ni ọgbà ti Isaiah n kọrin nipa rẹ̀. Abrahamu ni a kọ ṣeleri ilẹ yii fun; lẹyin eyi, nigba ijọba Sọlomọni ọba, awọn eniyan n gbé ọ̀pọlọpọ ninu rẹ̀. Bi awọn Ọmọ Israẹli bá gbọran si aṣẹ Ọlọrun, kò si ẹni kan ti i ba lagbara lati gbà á lọwọ wọn.

Ọlọrun ti ṣa awọn “okuta” (tabi awọn keferi) kuro ninu “ọ̀gba àjara” naa. O ti lé awọn orilẹ-ède keferi kuro niwaju awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn dé Ilẹ Kenaani. Kiki awọn Ọmọ Israẹli nikan ni Ọlorun n fẹ ki o maa gbé nibẹ. Bi wọn ba ti ṣe gẹgẹ bi Oun ti fẹ ki wọn ki o ṣe, igbesi-ayé wọn i ba kún fún ibukun, wọn i ba si ṣẹgun gbogbo ọ̀tá.

### Eso Kíkan

Ọlọrun kà awọn eniyan Rẹ̀ si “ayànfẹ àjara” Rẹ̀. O gbìn wọn si ilẹ Kenaani, O si fi ohun rere gbogbo tẹ́ wọn lọrun. Ṣugbọn nitori pe Israẹli pẹyinda si Ọlọrun, Ọlọrun wi pe, “O si wò pe ki o so eso, ṣugbọn eso kikan li o so.” Wò o bi ijatilẹ̀ naa ti pọ̀ tó!

Bawo ni ọkàn rẹ yoo ti ri bi iwọ ba ti ṣe wahala gidigidi lati ṣà okuta kuro ninu ilẹ kan, ti o si jẹ́ pe ọwọ ni iwọ fi ṣà okuta wọnni lọkọọkan; ti iwọ si ṣe ọgbà yi i ká, ti o si gbin aṣayan àjara, ti o si ṣe ibi-ifunti sinu rẹ̀ pẹlu lati fi fún eso rẹ̀; lẹyin gbogbo wahala yii, nigba ti iwọ fẹ kórè ohun-ọ̀gbin rẹ ki iwọ wa ri pe kiki eso kikan ni o wà nibẹ. Iwọ kò ri ohun kan mu jade pẹlu gbogbo iṣẹ-aṣekara ati inawo rẹ. Otubantẹ! Ohun ti Ẹni ti a sọrọ rẹ̀ ninu orin yii ṣe gan ni iwọ naa yoo fẹ ṣe: iwọ yoo wò ọgbà rẹ̀ lulẹ̀, iwọ yoo si fi i silẹ fun èpo lati hù sibẹ ki awọn ẹranko si maa gbé ibẹ.

### Idajọ Otitọ

Gẹgẹ bi o ti tọ, Ọlọrun pe Israẹli ati Juda lati ṣe idajọ ọràn ajara naa: “Kini a ba ṣe si ọ̀gba àjara mi ti emi kò ti ṣe ninu rẹ̀?’ Iwọ ha le ronu ohun miiran ti o yẹ ki Oun ki o ṣe si ọgbà ajara yii ki o ba le mu eso rere jade wa?

Iwọ ha le ronu ohun miiran ti o yẹ ki Ọlọrun ṣe lati mu ki Israẹli eniyan Rẹ̀ ṣe rere gẹgẹ bi orilẹ-ède? O mú wọn jade lati ilẹ Egipti wá, nigba ti wọn jẹ orilẹ-ède ti o wà labẹ isinru; O si fun wọn ni ilẹ eleso eyi ti a ti kọ́ tẹlẹ. O lé awọn ọta wọn kuro niwaju wọn. O sọ fun wọn pe awọn ni yoo maa ṣe ori, awọn orilẹ-ède iyoku yoo si jẹ ìrù. O fi isin otitọ lé wọn lọwọ, Ọlọrun kan ti O n gbọ́ adura wọn ti O si n dahun. Gbogbo nnkan wọnyii ni Ọlọrun ṣe fun awọn eniyan Rẹ̀.

Nigba ti Ọlọrun fẹ ki wọn ṣe ohun kan fun Oun – lati waasu igbala fun gbogbo ayé -- wọn kọ̀ wọn si n bọriṣa. Wọn gbagbe Ọlọrun, bẹẹ ni ọkàn wọn si kún fún ibi nigba gbogbo. Wọn kò tilẹ ni ifẹ si ara

wọn. "O reti idajọ, ṣugbọn kiyesi i, inilara; o si reti ododo; ṣugbọn kiyesi i, igbe." Igbesi-ayé wọn si dabi ilẹ aṣalẹ̀ ti Ọlọrun dá òjo rẹ̀ duro.

**Kò si Òjo**

Ọlọrun ti kilọ fun wọn nigba ti wọn fi Egipti silẹ nipa ohun ti yoo ṣẹlẹ si wọn bi wọn bá yipada kuro lẹyin Rẹ̀. Ọ̀kan ninu rẹ̀ ni pe Oun yoo dawọ òjo duro. Ọlọrun a maa jẹ ki òjo rọ̀ nigba ti O ba fẹ́; bi O ba si sé e mọ́, òjo ki yoo si rọ̀. Kò si ohun ti o le hù bi kò ba si omi, nitori naa ilẹ Kenaani di aṣalẹ. Kò si ẹni ti o fẹ́ lati gbé inu rẹ̀, bẹẹ ni awọn Ọmọ Israẹli (ti a n pe ni Ju) ṣi kuro nibẹ. O tilẹ ṣoro fun awọn Larubawa ti o wà nibẹ lati ri koriko fun awọn ẹṣin ati rakunmi wọn, ọ̀pọlọpọ ninu wọn si palẹ agọ wọn mọ́, wọn si ṣi kuro nibẹ. Bẹẹ ni ilẹ ti i ba jẹ́ ọgbà-àjara eleso si pada si aṣalẹ̀ alaileso. Fun ọdún pupọ ni ilẹ Palẹstini wà laileso, gẹgẹ bi ijiya nitori pe awọn Ọmọ Israẹli kọ Kristi silẹ.

**Ifẹ Ọlọrun si Wa**

Ẹ jẹ ki a ṣe aṣaro nipa ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun wa. O ran Jesu Ọmọ bibi Rẹ̀ kan ṣoṣo lati kú fun wa. Ofin Rẹ̀ ni eyi, "Ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú." Olukuluku eniyan ni o ti dẹ́ṣẹ̀ ri ti o si yẹ si ikú, ṣugbọn Jesu yọọda lati kú dipo wa. Wò bi o ti yẹ ki a kún fún ọpẹ́ tó, pe Jesu ṣetan lati gbà ìyà ti wa jẹ. Ṣugbọn a ni lati ni ifẹ lati tọ Ọ wá ki a si gbà wa là, bi bẹẹ kọ́ a o jiya.

Ọpọlọpọ eniyan ni o kọ̀ lati wá Igbalà. Jesu n sọkun lori wọn gẹgẹ bi O ti sọkun lori Jerusalẹmu ọlọ̀tẹ̀: "Jerusalemu, Jerusalemu, ..igba melo li emi nfẹ radọ bò awọn ọmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ̀ bò awọn ọmọ rẹ̀ labẹ apá rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ!" (Matteu 23:37). Ẹwẹ, O tun n beerè pe, "Kini a ba ṣe .. ti emi kò ti ṣe?" Ki ni Jesu i ba tun ṣe lati mú ẹlẹ̀ṣẹ wá si ironupiwada ki O si mu wọn lọ si Ọrun?

**Itọni**

Jesu wá si ayé lati fi ilana iye hàn wá. Bibeli sọ fun wa bi O ti ṣe lo igbesi-ayé Rẹ̀, O si fẹ ki a dabi Oun. A kò le sọ pe a kò mọ̀ bi awa i ba ti ṣe maa huwa. O fi akọsilẹ Ọrọ Rẹ̀ fun wa lati kọ́ wa nipa ohun gbogbo ni ayé.

Lẹyin eyi nipa ikú Rẹ̀ lori oke Kalfari, ati Ẹjẹ ti O ta silẹ, O fun wa lagbara lati maa gbé igbesi-ayé ailẹṣẹ. Ki ni o kù ti Oun i ba tun ṣe.

**Kikú fun awọn Ọta Rẹ̀**

Bọya o ti maa n gbọ́ pe ẹni kan fi ẹmi rẹ̀ lelẹ̀ fun awọn ọrẹ rẹ̀. Ṣugbọn iwọ kò le nireti pe ẹni kan le kú fun ọ̀tá rẹ̀. Jesu ṣe bẹẹ. Paulu Apọsteli sọ fun wa pe: "O ṣọ̀wọn ki ẹnikan ki o to kú fun olododo: .. Ṣugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" (Romu 5:7, 8). Jesu kú fun awọn ọ̀ta Rẹ̀ nitori pe O fẹ́ wọn O si fẹ gbà wọn là.

Kò ha tọ fun wa lati yara jẹ́ ipè Rẹ̀? O ti ṣe gbogbo eyi ti O le ṣe lati gbà wa lọwọ ọrun apaadi. O n pè nisisiyi pe: "OLUWA wipe, wá nisisiyi, ki ẹ si jẹ ki a sọ asọyé pọ̀: bi ẹ̀ṣẹ nyin ba ri bi òdodó, nwọn o si fun bi òjo-didi" (Isaiah 1:18).

**Ijiya fun Aigbọran**

Idajọ wọnni ti Ọlọrun pinnu sori awọn Ọmọ Israẹli yoo wá sori olukuluku ẹni ti o ba yipada kuro lọdọ Rẹ̀. O wi pe, "Egbe ni fun awọn ti ima dide ni kùtukutu, ki nwọn le ma lepa ọti lile; ti nwọn wà ninu rẹ̀ titi di alẹ, titi ọti-waini mu ara wọn gbona!" Awọn ẹlomiran rò pe kò si ohun ti o buru ninu mimu ọti lile, bi wọn kò ba ti mu amupara; ṣugbọn wolii nì tun wi pe: "Egbe ni fun awọn ti o ni ipá lati mu ọti-waini, ati awọn ọkunrin alagbara lati ṣe adàlu ọti lile!" Bi wọn tilẹ lagbara lati mu ọti lai mu amupara, sibẹsibẹ ohun ti o lodi ni. Ọrun apaadi ti ṣi ọgbun rẹ̀ silẹ lati gbà iru awọn ẹlẹṣẹ bẹẹ, ati awọn miiran pẹlu.

Ọlọrun wi pe eṣu ati awọn angẹli rẹ̀ ni a pese ọrun apaadi silẹ fun lati atetekọṣe; ṣugbọn bi awọn eniyan ba kọ̀ lati ri igbalà, awọn pẹlu yoo lọ sibẹ.

Ọlọrun gegun fun awọn ti n pe ibi ni rere, ati rere ni ibi. Ọpọlọpọ ibi ni o wà ni aye nisisiyi ti awọn eniyan n pe ni ẹ̀ṣẹ gbajumọ. Ṣugbọn ranti pe bi Ọlọrun ba sọ pe ohun kan kò dara, eyi nì ni pe kò dara, lai ka ohun ti awọn eniyan n wi nipa rẹ̀ si nnkan.

Ọlọrun gegun pẹlu fun awọn ti o n gba abẹtẹlẹ lati bo ẹ̀ṣẹ mọlẹ -- awọn ẹni ti "o da are fun ẹni-buburu nitori ère." Nigba ti a ba kà akọsilẹ nipa ẹ̀ṣẹ igba-ayé awọn Ọmọ Israẹli, bakan naa ni o ri pẹlu ẹ̀ṣẹ awọn eniyan lode oni. "Nitorina ni ibinu OLUWA fi ràn si enia rẹ̀."

A kò fẹ ki eyikeyi ninu idajọ ègún wọnyii ki o wá sori wa, nitori naa ẹ jẹ ki a fi ọkàn wa fun Ọlọrun nigba ọ̀dọ́ wa. Ẹ jẹ ki a maa rin pẹlu ikiyesara ni gbogbo ọjọ-ayé wa, ni igbọran si Ọrọ Rẹ̀, ki a ba le ni ibukun Ọlọrun nihin ni ayé ati awọn ti o ti lọ pese silẹ fun awọn ti wọn fẹ Ẹ.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni a fi Israẹli wé ninu orin yii?

2 Ṣapejuwe ohun ti Ọlọrun ṣe si ọgbà-àjara Rẹ̀.

3 Ki ni O ri nigba ti O n reti eso?

4 Ki ni "awọn okuta" duro fun?

5 Ki ni iyà ti a pinnu sori ọgba-ajara nì?

6 Ki ni ohun ti Jesu ṣe fun wa?

7 Ki ni ṣe ti "ipò-okú ti fun ara rẹ̀ li àye"?

8 Darukọ diẹ ninu awọn ohun ti ègún Ọlọrun wà lori rẹ̀.

9 Ta ni a pè ki o ṣe idajọ laaarin Ọlọrun ati ọgbà-àjara Rẹ̀?